**35.** Nwọn o ma wo ran, lori ibusun.

عَلَى ٱلْأَرَآئِكِ يَنظُرُونَ ﴿٣٥﴾

**36.** Njẹ a san awọn alaigbagbọ ni ẹ san ohun ti nwọn se nisẹ?

هَلْ ثُوِّبَ ٱلْكُفَّارُ مَا كَانُوا۟ يَفْعَلُونَ ﴿٣٦﴾

## *(84) Suratul - Inşikọki*

سُورَةُ الانْشِقَاقِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Nigbati sanma ba bu pẽ.

إِذَا ٱلسَّمَآءُ ٱنشَقَّتْ ﴿١﴾

**2.** Yio si gbọ ti Oluwa rẹ̀; yio si mu u şe nişẹ ni bi oti jẹ dandan fun u lati se.

وَأَذِنَتْ لِرَبِّهَا وَحُقَّتْ ﴿٢﴾

**3.** Ati nigbati nwọn ba ngbà ilẹ̀ laye si i.

وَإِذَا ٱلْأَرْضُ مُدَّتْ ﴿٣﴾

**4.** Ti yio ju gbogbo ohun ti o wa ninu rẹ̀ sita ti yio şofo.

وَأَلْقَتْ مَا فِيهَا وَتَخَلَّتْ ﴿٤﴾

**5.** Yio si gbọ ti Oluwa rẹ̀; yio si mu u şe nişẹ ni bi oti jẹ dandan fun u lati se.

وَأَذِنَتْ لِرَبِّهَا وَحُقَّتْ ﴿٥﴾

**6.** Irẹ enia dajudaju o jẹ olugbiyanju lati pade Oluwa rẹ ni igbiyanju gidi; o si pade rẹ.

يَٰٓأَيُّهَا ٱلْإِنسَٰنُ إِنَّكَ كَادِحٌ إِلَىٰ رَبِّكَ كَدْحًا
فَمُلَٰقِيهِ ﴿٦﴾

**7.** Ẹniti o ba fi ọwọ-ọtun gba akọlẹ̀ tirẹ̀.

فَأَمَّا مَنْ أُوتِىَ كِتَٰبَهُۥ بِيَمِينِهِۦ ﴿٧﴾

**8.** Nigbana oniyẹn a o ba a şiro (işẹ rẹ) ni işiro ti o rọrũn.

فَسَوْفَ يُحَاسَبُ حِسَابًا يَسِيرًا ﴿٨﴾

**9.** Atipe yio pada wa ba awọn enia rẹ ni ẹniti ndunnu.

وَيَنقَلِبُ إِلَىٰٓ أَهْلِهِۦ مَسْرُورًا ﴿٩﴾

**10.** Atipe ẹniti a ba gba ẹhin fun ni akọlẹ̀ tirẹ̀.

وَأَمَّا مَنۡ أُوتِيَ كِتَٰبَهُۥ وَرَآءَ ظَهۡرِهِۦ ١٠

**11.** Yio ke ibosi egbé.

فَسَوۡفَ يَدۡعُواْ ثُبُورٗا ١١

**12.** Yio si wọ ina jonijoni.

وَيَصۡلَىٰ سَعِيرًا ١٢

**13.** Dajudaju o ti wa larin awọn enia rẹ̀ ti o ndunnu.

إِنَّهُۥ كَانَ فِيٓ أَهۡلِهِۦ مَسۡرُورًا ١٣

**14.** Dajudaju on ro pe on kò ni pada (si ọdọ Oluwa rẹ̀).

إِنَّهُۥ ظَنَّ أَن لَّن يَحُورَ ١٤

**15.** Bẹẹni, dajudaju Oluwa rẹ̀ ti ri i.

بَلَىٰٓۚ إِنَّ رَبَّهُۥ كَانَ بِهِۦ بَصِيرٗا ١٥

**16.** Mo fi awonpapa-sanma bura.

فَلَآ أُقۡسِمُ بِٱلشَّفَقِ ١٦

**17.** Ati oru ati ohun ti o nba a rin.

وَٱلَّيۡلِ وَمَا وَسَقَ ١٧

**18.** Ati oşupa nigbati o ba degba (ti imọlẹ rẹ ba pe).

وَٱلۡقَمَرِ إِذَا ٱتَّسَقَ ١٨

**19.** Dajudaju ẹnyin yio ma ti ipele kan wọ ipele kan.

لَتَرۡكَبُنَّ طَبَقًا عَن طَبَقٖ ١٩

**20.** Kinişe wọn ti nwọn kò fi gbagbọ lododo?

فَمَا لَهُمۡ لَا يُؤۡمِنُونَ ٢٠

**21.** Atipe nigbati a ba nke Al-Kurani fun wọn, nwọn ki fi ori balẹ̀.

وَإِذَا قُرِئَ عَلَيۡهِمُ ٱلۡقُرۡءَانُ لَا يَسۡجُدُونَۤ۩ ٢١

**22.** Bẹẹkọ, awọn alaigbagbọ ni nwọn npe (e) nirọ.

بَلِ ٱلَّذِينَ كَفَرُواْ يُكَذِّبُونَ ٢٢

**23.** Atipe Ọlọhun lo mọ̀ julọ nipa ohun ti nwọn gbe pamọ (sinu ọkàn wọn).

وَٱللَّهُ أَعۡلَمُ بِمَا يُوعُونَ ٢٣

**24.** Nitorina fun wọn niro iyà ẹlẹtaelero.

فَبَشِّرۡهُم بِعَذَابٍ أَلِيمٍ ٢٤

**25.** Ayafi awọn ti nwọn ni igbagbọ ododo ti nwọn nṣe iṣẹ rere, ẹsan ti kò ni lopin ni ti wọn.

إِلَّا ٱلَّذِينَ ءَامَنُواْ وَعَمِلُواْ ٱلصَّٰلِحَٰتِ
لَهُمۡ أَجۡرٌ غَيۡرُ مَمۡنُونِۭ ٢٥

## *(85) Suratul - Burũji*

سُورَةُ ٱلۡبُرُوجِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi sanma oni «burũji» bura.

وَٱلسَّمَآءِ ذَاتِ ٱلۡبُرُوجِ ١

**2.** Ati ọjọ ti a ṣe adehun nã (bura).

وَٱلۡيَوۡمِ ٱلۡمَوۡعُودِ ٢

**3.** Ati olujẹri ati ohun ti njẹri le lori.

وَشَاهِدٖ وَمَشۡهُودٖ ٣

**4.** A ṣẹbi le awọn ti o gbẹ koto.

قُتِلَ أَصۡحَٰبُ ٱلۡأُخۡدُودِ ٤

**5.** Ina ti nwọn nko.

ٱلنَّارِ ذَاتِ ٱلۡوَقُودِ ٥

**6.** Nigbati nwọn joko si eti rẹ.

إِذۡ هُمۡ عَلَيۡهَا قُعُودٞ ٦

**7.** Atipe nwọn jẹri si ohun ti nwọn ṣe fun awọn onigbagbọ ododo.

وَهُمۡ عَلَىٰ مَا يَفۡعَلُونَ بِٱلۡمُؤۡمِنِينَ شُهُودٞ ٧

**8.** Kòsi ohun ti nwọn tori rẹ jẹ wọn niyà fun ju pe nwọn gba Ọlọhun gbọ, Alagbara, Ẹniti ọpẹ tọ si.

وَمَا نَقَمُواْ مِنۡهُمۡ إِلَّآ أَن يُؤۡمِنُواْ بِٱللَّهِ
ٱلۡعَزِيزِ ٱلۡحَمِيدِ ٨

**9.** Ẹniti O ni ijọba ti sanma ati ilẹ. Atipe Ọlọhun ni Ẹlẹri lori gbogbo nkan.

ٱلَّذِي لَهُۥ مُلۡكُ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِۚ
وَٱللَّهُ عَلَىٰ كُلِّ شَيۡءٖ شَهِيدٌ ٩